# Bon Secours Health System, Inc.
# Iwe Owó Ìrànwọ́ Ni Ṣoki

Èròngbà ile iṣẹ Bon Secours Health System Inc., (BSHSI) ni lati pese eto ilera to ni oju aanu, ti o peye fun awọn to nilo rẹ, boya wọn lagbara lati sanwo tabi wọn ko lágbára. BSHSI nṣe iranwọ owo fun awọn alaisan ti wọn ni eto adojutofo ati awọn ti ko ni eto adojutofo ti wọn ngba itọju pajawiri ati awọn itọju miran to nilo eto ilera ni eyikeyi awọn ile iwosan wa.

**<u>Tani o yẹ fun owó ìrànwọ́?</u>**

Eto iranwọ owo BSHSI (Financial Assistance Policy, "FAP") ńpèsé ida ọgọrun ninu ọgọrun (100%) iranwọ owo fun itọju pajawiri tabi awọn itọju eto ilera miran fun awọn alaisan ti wọn ni eto adójútòfò ati awọn ti ko ni eto adójútòfò ti owo osu gbogbo mọlẹbi wọn fun ọdun kan dọgba tabi kere si ida ọgọrun meji ninu ogọrun (200%) awọn Ilana ijọba apapọ fun àìnị (Federal Poverty Guidelines, FPG) lọwọlọwọ. BSHSI tun ṣe eto ẹdinwo fun awọn alaisan ti owo osu awọn mọlẹbi wọn fun odindi ọdun jẹ laarin ida ọgọrun meji o lekan ninu ida ọgọrun (201%) si ida irinwo ninu ida ọgọrun (400% ) ninu eto FPG. Ẹni to ba yẹ fun eto FAP tabi ẹni ti o ba ni eto adojutofo tabi ẹni toni eto adojutofo ti ko lẹtọ si eto iranwọ owo ko nii san owo to ju iye owo ti o pọn dandan fun gbogbo alaisan lati san (amounts generally billed, AGB) lọ fun itọju pajawiri tabi awọn itọju eto ilera to yẹ fun awọn alaisan ti wọn ni eto adójútòfò fun awọn itọju bẹẹ.

**<u>Bi ẹ ṣe lee beere fun owó ìrànwọ́?</u>**

Ẹni to ba ni iporuuruu nipa agbara wọn lati lee san owo fun itọju pajawiri ati itọju eto ilera to yẹ (medically necessary care) lee beere fun owó ìrànwọ́. Lati beere fun owo iranwọ, ki alaisan (tabi awọn ẹbi wọn tabi awọn oluranlọwọ wọn miran) fọwo si iwe ìbéèrè fun owo iranwọ wa. E le ri awọn ẹ̀da iwe ibeere fun owo iranwọ ati FAP nipa pipe ẹka itọju oníbàárà pẹlu ẹrọ ibanisọrọ: (Lábẹ́lé) 804-342-1500 tabi (Ipe laisan owo) 877-342-1500. Ẹ ṣi le gba iwe ibeere fun owo iranwọ ati FAP lọfẹ nipa fifi lẹta ranṣẹ si Eto Owó Ìrànwọ́ Bon Secours RGH (Bon Secours RGH Financial Assistance program), Apoti Ifiweranṣẹ :742431 Ilu Atlanta GA, 30374-2431. Nipari, ẹ le tẹ ẹda iwe Ibeere fun Owó Ìrànwọ́ ati FAP lọfẹ lori ikanni ayélujára wa: www.fa.bonsecours.com.

**<u>Nibo ni mo ti le ri iranlọwọ gba lati le kọ iwe ìbéèrè fun owó ìrànwọ́?</u>**

Ẹni to ba fẹ iranlọwọ nipa kikọ iwe ibeere fun owó ìrànwọ́ le pe ẹka itọju oníbàárà lori awọn ẹrọ ibanisọrọ to wa ni isalẹ yii.

**<u>Awọn itọju wo lo wa fun?</u>**

Gbogbo eto itọju pajawiri to nilo iwosan ni o lẹtọ si eto FAP, pẹlu eto itoju awọn alaisan ti wọn ko ni sun ile iwosan (outpatient services), eto itoju awọn alaisan ti wọn ńsun ile iwosan (inpatient care), ati awọn eto itọju ninu iyara pajawiri (emergency room services). Awọ itọju ti ko lẹtọ bii awon ilana ti ko nilo iwosan, itọju nipa iṣe ara lóge ati ilana idiyele fun gbogbo alaisan, awọn alaisan ti wọn ko fẹ lo eto adojutofo wọn, awọn ohun elo ile iwosan to tọ́jọ́, itoju ninu ile, awọn itọju ti a nṣe fun awọn to ni ijamba ati awọn oogun ti ko si labẹ eto iranwọ owo. Ti alaisan ko ba ni ẹni to le san owo itọju fun ijamba, alaisan bẹ le beere fun owó ìrànwọ́. Owo iṣẹ awọn Dokita ati awọn Onimọ ti wọn kii ṣe oṣiṣe BSHSI , ti wọn si nṣiṣẹ itọju ni ile iwọsan wa le ma wa ni ibamu pẹlu eto owó ìrànwọ́ BSHSI. Ba Dokita rẹ sọrọ tabi ki o lọ si ori ikanni ayelujara wa to wa ni: www.fa.bonsecours.com lati mọ boya Dokita rẹ nkopa ninu eto owó ìrànwọ́ BSHSI.

**<u>Kini yoo ṣẹlẹ ti mo ba ni awọn ìbéèrè tabi ti mo ba nilo iranlọwọ lati kọ iwe ìbéèrè?</u>**

Ti o ba nilo iranlọwọ, o lee kan si oludamoran fun eto owo tabi olukawo to wa ni awọn ile iwosan wa tabi ki o pe ẹka itọju oníbàárà wa lori awọn nọmba erọ ibanisọrọ wọnyi (Lábẹ́lé) 804-342-1500 tabi (Ipe laisan owo) 877-342-1500. Ẹ le tun gba iranwọ ti ẹ ba yọju si eyikeyi awọn ibi iforukọsilẹ fun ile iwosan wa tabi ki ẹ ri eyikeyi ninu awọn oludamoran fun eto owo tabi olukawo ti wọn wa ni awọn ile iwosan wa. Fun awọn alaisan ti ko gbọ ede Gẹẹsi, awọn itumọ iwe yi si awọn ede miran, iwe FAP ati iwe ibeere fun owó ìrànwọ́ wa ni oriṣiriṣi ede, pẹlu ede Gẹẹsi ati ati Spanish. Jọwọ pe awọn nọmba ẹrọ ibanisọrọ to wa loke yii tabi ki o lọ sori ikanni ayelujara wa lori: www.fa.bonsecours.com lati gba ìtúmọ̀ si ede miran ni soki, BSHSI FAP ati iwe ìbéèrè eto owó ìrànwọ́.